**Ijọ́ Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu**
**Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nàìjíríà**
**ÌSÌN OMI MÁNNÀ**
**Kókó Àdúrà – ÌWÒSÀN PÍPÉ (11)**

**Ìjẹ́wọ́: Orín Dáfídì 147:3: O mú awọn onírora àyà lára dá: Ó di ọgbẹ́ wọn.**

**Orin Ìyìn àti Ìjọ́sìn**

1. Afúrúgbìn irúgbìn búburú lòdì sí àláfíà mi, kú, ní orúkọ Jésù.
2. Iná Ọlọ́run, pa gbogbo ibùjókò ìwà ìkà tí wọ́n yàn lòdì sí àláfíà mi run, ní orúkọ Jésù.
3. Àwọn ibùjókò ìwà ìkà tí wọ́n gbé dìde lòdì sí ìtẹ̀síwájú mi láyé, gba iná, ní orúkọ Jésù.
4. Bàbá Olúwa, jẹ́ kí gbogbo ìlànà àìsàn àjogúnbá tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayé mi, yangbẹ nípa iná, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ibùkún ìdílé mi, ayé mi, ìgbéyàwó mi àti òwò mi tí ibi gíga àjẹ́ ti jẹ run, gba ìtúsílẹ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ìtẹ́ ìwà ìkà ní àyíká mi, gba ifàlulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ìtẹ́ àjẹ́ tó n fò lágbégbè mi, di wíwó lulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
8. Àwọn ìtẹ́ ìwà ìkà tí wọ́n gbékalẹ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi, wólulẹ̀, ní orúkọ Jésù.
9. Olúwa, jẹ́ kí ìtẹ́ Jésù Krístì fìdímúlẹ̀ ní gbogbo agbègbè ayé mi, ní orúkọ Jésù.
10. Lónì, nísisìyí àti títí láí, mo gba ẹnubodè àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
11. Olúwa, fi ìgbálẹ̀ ìparun Rẹ gbá ibùgbé ìwà ìkà nínú ilé bàbá mi dànù, ní orúkọ Jésù.

12. Nípa iná, mo mú kọ́kọ́rọ́ àlùmọ́nì tó ma ṣemílóóre, kúrò ní ìkáwọ́ ìpọ́njú tí àwọn àjẹ́ ṣagbátẹrù rẹ̀, ní orúkọ Jésù.
13. Olúwa, sọ mí di ẹ̀rùjẹ̀jẹ̀ nlá sí àgọ́ àwọn ọ̀tá mi, ní orúkọ Jésù.
14. Mo gba ibùkún mi kúrò ní ọwọ́ àwọn akónilẹ́rù búburú, ní orúkọ Jésù.
15. Gbogbo ìkán ẹ̀jẹ̀ mi nínú àjọ àjẹ́, tí wọ́n nlò láti dá ayànmọ́ mi lóró, gba iná, ní orúkọ Jésù.
16. Mo lé jáde, mo sì dáná sun gbogbo ẹgbẹ́ ogun àjẹ́ tí wọ́n yàn lòdì sí ayé mi, ní orúkọ Jésù.
17. Gbogbo kòkòrò àjẹ́ nínú ẹ̀jẹ̀ mi, kú, ní orúkọ Jésù.
18. Ìṣàn búburú àjẹ́ nínú ẹ̀jẹ̀ mi, gbẹ dànù nípa iná, ní orúkọ Jésù.
19. Ọ̀pá ìwà ìkà tó n ṣiṣẹ́ lòdì sí ayé mi, fọ́ sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
20. Odù àjẹ́ tí wọ́n lò lòdì sí ayé mi, fọ́ sí wẹ́wẹ́, ní orúkọ Jésù.
21. Gbogbo igbó òkùnkùn, tó nfi àwọn ohun-ìjà ìwà ìkà pamọ́ lòdì sí mi, jó di éérú, ní orúkọ Jésù.